# WON FE BAIYE JE, WON MU OBINRIN WO IGBALE


**Ogun Ita'ja**

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kia L'oja o ta.


# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO


**ENYIN IJO MUSULUMI IRE DE**

Adua ti a npe ni Duau Alfauzul Albazin o ni anfani pupo o si le mu ilosiwaju wa, o dara ki o ni ni ile. Anta ni 2/6d eyo, 18/- fun dozini

Ti e ba fe Tira yi e wa si odo:-

Alhaji M. A. OPELOYERU
37, Itolo Street Lagos.



VOL. X No. 581. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, JULY 19, 1958. KOBO MEJI (2d)


## Won Fe Baiye Je Nilu Jos, Won Mu Obinrin Wo Igbale

JOS. Afihan ti nwon nse nisisiyi nilu Jos ni orisirisi aworan ati Ere ile Yoruba bi ti Egungun ati Gelede ni nwon nfihan nibe.

Okan ninu awon Alafihan na so ninu oro re wipe awon alaimokan enia ma nro wipe awon okunrin nfi Egungun ati Gelede se ideruba fun awon obinrin ni, lati ma fi j'eru, nitorina ni awon fi se afihan yi, ki oro ati se rlaye fun awon enia wipe ohun ti awon enia nsin ni atipe ere ni awon fi nse nile Yoruba.

Orisirisi aworan ti o mbe nibe le ni adorin pelu ori awon eranko ti awon afi han.

## Oloye Oluwa D'ologbe

EKO. Oloye Alhaji Amodu Tijani Oluwa se alaisi ni ile re ni Isale Eko ni ojo ose ti ise ojo ketala osu July 1958, nigbati o d'agba di omo adorun-odun (90 years) l'aiye. Oloye Alhaji Amodu Tijani Oluwa ni agba ati asiwaju fun gbogbo Oloye ilu Eko. okan pataki ni ninu awon Idejo—awon Oloye onile ilu Eko.

Oloye Oluwa yi je omo bibi inu Ologbe Oloye Amore Oluwa o si je onisowo ekuro o je oye ni ojo keta osu April ninu odun 1915. Nigbati o di inu osu May ni odun 1920 ni o lo silu Oyinbo fun ejo kotemilorun ti ile re to wa ni Apapa, Ologbe Herbert Macaulay "Ejo nigboro"" ni akowe re ti o mu lo, o si jare ejo re na ki o to pada wa sile ninu osu October odun 1921



Lasiko ti o lo silu Oyinbo na ni awon mu lo foju kan Oba ilu Oyinbo George Ekarun ninu ogba Elefo nilu nla London. Alhaji Tijani Oloyo Oluwa yi je pataki ninu awon igi-lehin ogba fun egbe bombata "Demo" ti Ologbe Herbert Macaulay da sile nilu Eko aiye rere ijoun. Alhaji Amodu Tijani Oloye Oluwa fi obinrin re ati omo metala sile laiye.

A sin oku Alhaji Tijani Oloye Oluwa tilu Eko siwaju Mosalasi re ninu agbole Oluwa ni Isale Eko Ese awon enia pataki-pataki ni o pe sibe awon eni bi Sir Kofo Abayomi S L Akintola Dr Akerel Doherty (Oloye otun Eko) Dr Akinola Maja Oloye Baba - Eko Dr Omololu Alhaji Mohammadu Ribadu Oloye Bayo Doherty Councillor A O Lawson ati opo enia ti ako le daruko tan.

## Azikiwe Yio F'oju Kan Balewa



ENUGU. Ikede Ijoba Ila-Orun jade wipe Alakoso Ijoba, Olola Dokita Azikiwe pelu awon alabasise re yio wa f'oju kan Alhaji Tafawa Balewa, Alakoso Ijoba apapose nilu Eko ni ojo kejidinlogbon osu yi fun asaro pataki.

## E K'abo o



Olola Gomina ti gbogbo Nigeria pada de lati ilu re ti o ti gba isinmi osu meta lo pelu Olola Omidan Iyawo re. Won ba oko ofurufu gunle si Ikeja l'owuro ojo 16th July 1958

E k'abo o,
Alafia k'ed, ni ?

## Akiyesi Pataki

A fi eyi kede fun gbogbo enyin Asoju Iwe Irohin wa nile Yoruba, l'oke Oya, nile Ibo, l'oke Okun ati nilu Oyinbo wipe enikeni ti ko ba fi owo wa ranse ki osu to pari ao ko oruko re fun Loya Eleti-Ofe, ao ba se ejo ao si gba owo iwe ese lowo re.

No 73/S 2/Vol 1X/702

## Ministry Of Home Affairs and Mid-West Affairs Information Division Western Region.

VACANCY FOR ONE ASSISTANT SOUND ENGINEER

Applications are invited from suitable candidates to fill the post of one Assistant Sound Engineer in the Film Production Unit of the Information Division of the Ministry of Home Affairs and Mid-West Affairs, Western Region Ibadan.

SALARY SCALE :- C [T] Training 1, 2. £288 - 744.

Post pensionable and permanent

For full particulars and method of application please see Western Region of Nigeria Gazette No 46 Vol 7 Notice No 649 of 10th July 1958.

CLOSING DATE; 31st July 1958

No 73/S 2/Vol 1X/702

## Ministry Of Home Affairs and Mid-West Affairs Information Division Western Region

VACANCY FOR CAMERAMAN

Applications are invited from suitable candidates to fill the post of Cameraman in the Film Production Unit of the Information Division of the Ministry of Home Affairs and Mid-West Affairs, Western Region Ibadan.

SALARY SCALE:- C (T) 2; 3, 4; £570 - 1014.

Post pensionable and permanent.

For full particulars and method of application, please see Western Region of Nigeria Gazette No. 46 Vol 7, Notice No. 648 of 10th July, 1958.

CLOSING DATE· 31st JULY 1958.

## Baba Fun Awon Omo Re Ni Egbogi Aran o Di Ijogbon

IBADAN Baba kan ti o bi awon ọmọ mejọ lo pe awọn ọmọ rẹ na jọ, o si fun wọn ni egbogi aran mu. Gẹrẹ ti awọn ọmọ na mu egbogi yi tan, lo gbija ifọu wọn, de ipo ti ọkan ninu awọn ọmọ na ni lati fi aiye silẹ, eti awọn ọmọ meji di pata-pata, ọkan si daku gbọn-ran-gondan.

Ọkunrin ti o jẹ baba awọn ọmọde na tọ wipe, on rade awọn enia kan ti o rà egbogi oyinbo kakiri awọn lo ra egbogi na fun on wipe egbogi aran ni, ni on ba ra a. Bi on ti fun awọn ọmọ ni egbogi na mu ni awọn bẹrẹ amodi

Awọn ọlọpa tẹ siwaju lati ridi gbogbo asiri ti o ba pamọ nidi ọrọ yi. awọn si ti fi egbogi na ranṣẹ si ile egbogi ni Eko, lati ba ni yẹ iru egbogi aran to ṣeku na wo, yala ogun aran ni titọ tabi egbogi miran.

ITAN IGBESI AIYE ANOBI

Bere iwe itan igbesi aiye Anobi Muhammed ti a ti yi si ede Yoruba ati Iwe Kokuru-Kogun Ẹkọ nipa Irantiki ati ọrọnsọ Anọbi ati awọn orisisi iwe miran ni ti Islam.

Lọdọ:-
Alfaqhi Y. Kos. Oshishi
Alias Onitara Adini,
75, Docemo Street,
Lagos.

## Oba Obinrin Nri Alafia



Lati iwọn ọjọ diẹ sẹhin ni ti a gbọ wipe ọba obinrin ilu Oyinbo nṣe aisan, ati pe ẹsanri ni amodi na ki ntutu fẹrẹ to wọ ọ. Nigbiyi iroh'n ti a tun ri gbọ ni wipe o ti nri alafia. Kabiyesi, ki ọba ko pẹ, ajinde ara yio ma jẹ o.

## Iku la ba bo a ba forisa sile ejo eworo logbe weli-weli de o



# Kini Itumo Oro Nwonyi ?

OLOTU

Jowo gba mi laye lati bere alaye oro nwonyi lodo re nitori mo gbagbo pe ore na ni lati ye o ju mi lo. Awon oro na nwonyi:- Communist, Socialist ati Capitalist,

Emi ni.
Raphael Aberuagba

## Alaye Won Niyi Communist

Awon Ijoba Rosia ni a npe ni Communism, eyiti itumo je wipe ohungbogbo niti ijoba, ko si eniti o da ohun kan ni ni adabowo arare enikeni ti o ba fi ara mo ijoba yi ni a npe ni Communists,

## Socialists

Socialists Awon Ijoba Gesi ti o je ijoba alafia ni a npe ni Socialism eyiti itumo re je wipe ki a pin ohun gbogbo ni ogbogba, iyen nipe ohun ti Olukuluku ba ni tire ni ise eniti o ba fi ara mo Ijoba yi ni a npe ni Socialist

## Itumo Capitalist

Awon American lo ni owo lowo pupo ju ti awon si ni awon ohun isura lowo pupo bi wura Fadaka ati orisirisi okuta iyebiye ko si ara ti awon ko le fi owo da. Eyi nidi re ti awon se npe won ni Capitalist

**E Ma Ka Iwe Iroyin Eleti-Ofe Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re.**


*Story of a Successful Trader*

# Mr. N. S. Shofoluwe

## and The United Africa Company work together for prosperity





After leaving school in Lagos in 1924 Mr. N. S. Shofoluwe trained for 2 years to be a teacher. But then he saw opportunities in trading and joined the Niger Company. Today he is an important trader in Zaria with a very large turnover in stockfish, blankets, bicycles and other merchandise. He employs 3 storekeepers and many labourers.

As an employee of the Niger Company, and later The United Africa Company, Mr. Shofoluwe worked in many branches and gained valuable experience. In 1950 he became a Company trader in Zaria, in business on his own. With a flourishing business, his own home and the means to educate his children well he appreciates the help given him by the Company, with whose managers he is in daily touch. He looks forward to continuing his association with the Company for many prosperous years ahead.

*Hundreds of African traders rely on The United Africa Company to bring them goods from all over the world—and many of them started successful businesses with stock supplied on credit by the Company, helped by advice from its Managers. To The United Africa Company every trader is an important source of information on the needs of African buyers, so that both the trader and the Company profit by their friendship in business together.*



*THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED*

# ELETI OFE

A-NDU-YON ...KO SE WI L'EKO

EDITORIAL OFFICE & WORKS: 25, Koseko Street, Lagos. P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAM: "ELETI - OFE LAGOS" Phone 23379

VOL. NO. X. 551, LAGOS, SATURDAY JULY 19, 1958.


## Wo Bi Awon Alagbara Ti Nsubu..

Gbaka ... a gbo iku alagba, enı're Alhaji Amodu Tijani, Oloye Oluwa ti ilu Eko, eyiti o sele ni ojo ose (Sunday) ti ise ojo keta ... osu July 1958 ... ni Isale Eko. Alagba enieu're Oloye Oluwa to s'alaisi yi je ologbon ati enilakaye eniyan, ... lati ... awon opomulero ti ... ilu Eko ... nigba aiye rere Eko ijoun.

... awon eniyan, Herbert Macaulay, Branch Isale, Branch Ekuo, Saudi Adewale Bello Alufa (Alafa Bello Pro-fesor) Fasanya Akeju, Oloye Qbanikoro ti ilu Eko aiye ijoun, "okunrin ... ohun ... ti o ... lehin ... nle ... iwaju lo" awon ... eniyan ... ati awon ti ako le deruko ... won.

Ki Oluwa Olodumare gba ... oluk luku won si afe rere ki o si fori ese won jin won. Ki Iwaju ti awon ... fun won ki ehin ti awon fi sile ma baje emin.

Wo bi awon alagbara ti nsubu awon ohun ija si segbe!

---

## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamo e wo ni OMORELA o dara pupo fun awon omode.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun ... iko ati orisirisi ... mirali ti o ma nba omode ja ... asiko ... Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun ... won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode

OMORELA BABY MIXTURE

(Sile Mefa Abo 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lodo

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemists)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.

---

## N.C.N.C. Eko Ko Fara Mo Aje Mimu

EKO. Ogbeni Apalara ... fun awon ... Otu ... wipe, ki Oori ... Mbadiwe ... awon ... kj awon le mo ... o ... odele ... awon mejeji.

Eyi ni Ogbeni Benson ... wipe ... ko si ... kiri aje mimu ti ... oro ti o dele yi.

... Mbadiwe ba ... ile Ibo. Kola Balogun, H. O. Davies ati awon ... ti awon ... yi, sugbon ti awon je alatilehin fun Mbadiwe ako? Beni awon nwonyi ko nse Ibo.

Nitori idi eyi Ogbeni Benson ati awon omo egbe N. C. N. C. yio rin irin ajo lo si Pota, Owerri, Aba, ... ati Enugu lati la idi oro yi ye awon Ibo lati fi se atilehin fun alaye ti Dokita Azikiwe nse.

---

## Oku Olomo Gege Lao Gbe

Abule-Ado Irohin ko to afojuba nigbati iya wa Ayisatu Onike-Kosi fi da ile so aso bora. Oju gbogbo awon omo, omo-omo ara ati ebi lo peju sibi oku na awon ano pelu ko kere. Ni ojo Sunday 6th 1868 ni a bi iya wa yi, eigbati o si di eni ... odun gere lo fi ile aiye sile.

Nitu awon omo ti iya na fi sile ni Ogbeni M. Balogun ti o ... Alaga ijo Ansarudeen ti Soba A Salami Morinatu S ibu A Lasisi Lemomu Tesilimi Noiiyu Obaju-Ode Lawani Eni-Abata ni Olori ebi S A Abudu Oniwe-irolun Alufa Karaole Oniwasi Meliki Buramo ati Suberu Okokomaiko

Lojo ti oku na ku malu kan ni awon pa ni ojo kejo awon tun pa malu ko si eniti o de ibi oku na ti ko je ajeyo onje. Awon ijo Alufa ati Alhajaji se isin tiwon, nwon se wasi nwon ke Dalaileilu nwon ke yasin lehin eyi ni orisirisi egbe bere si de pelu ilu ati ijo. Die ninu awon gbajumo ti o wa sibi oku na ni Councilor Fadun ti ojo Alaworo ti Ilu Irewe ti Abule-ado Taiwo Olojo Aro Okokomaiko awon ara Akesan Ojo Ijanikin Amuwo Ijegba Snoba Ashogun Onireke Owode Kojere Agboroko. Awon egbe Bomode-ko ku egbe Olowo dun ba-lo

Ayisatu Olorisa Ogun de ibe wa korin, awon alapala ojo na gba iyi o gba eye

---

## Owe Yoruba

**Talo je fi odo Akoko gun iyan, talo je so leke opolo mo omo re lorun**

---


No 73/S 2/Vol IX/702

**Ministry Of Home Affairs and Mid-West Affairs Information Division Western Region**

VACANCY FOR ONE ASSISTANT CAMERAMAN

Applications are invited from suitable candidates to fill the post of one Assistant Cameraman in the Film Production Unit of the Information Division of the Ministry of Home Affairs and Mid-West Affairs, Western Region Ibadan.

SALARY SCALE:- C (T) Training. 1, 2; £288 - 744

Post pensionable and permanent.

For further particulars and method of application, please see Western Region of Nigeria Gazette No. 46 Vol 7, Notice No. 647 of 10th July, 1958.

CLOSING DATE: 31st JULY 1958.

No 73/S 2/Vol IX/702

**Ministry Of Home Affairs and Mid-West Affairs Information Division Western Region.**

VACANCY FOR SENIOR STORES ASSISTANT GRADE I

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the post of Senior Stores Assistant, Grade I. In the Information Division of the Ministry of Home and Mid-West Affairs, Western Region Ibadan.

SALARY SCALE - D.4, £390 X 18 - 444 X 24 - 492.

For further particulars and method of application please see Western Region of Nigeria Gazette No 48 Vol 7 Notice No 646 of 10th July 1958.

CLOSING DATE: 31st July 1958

## Ofin Okunrin Kan Wa'lu Tunis

TUNIS. A gbo irohin wipe ilu Tunis yi jẹ ilu Imale esin won gẹgẹbi aṣa Imale ko kọ ki ọkunrin kan ni obinrin mẹwa, Ṣugbọn Oniyigi ko gbọdọ tayọ mẹrin eyiti awọn npe ni Wahari.

Laipẹ yi ni awọn so ofin titun kan wipe lati ẹnu oṣu yi lọ gbogbo ọmọkunrin ilu na ko gbọdọ ni ju iyawo kanṣoṣo ayafi awọn olowo tabi awọn ti o ti niyawo pupọ siwaju ki a to ṣe ofin na.

Enikẹni ti o ba ru ofin yi yio lọ si ẹwọn ọdun kan.

## Kini Se Ti Ojo Odun Awon Musulumi Kofi Ndogba ?

Lati Owo Alufa Oshish.
[O bere ninu iwe wa ose to koja]

Ẹkẹrin. Nipa oṣu oju ọrun niti Ọlọrun, oṣu na si ni Musulumi ntele gegebi mo ti sọ lakọkọ, oṣu na si ni oju ọna mẹtala (13) ti o nrin ninu ọdun kan nigbati o ba rin si iha ila kan awọn nwonni yio tete ri ju awọn ara ilu yoku lọ, gegebi mo ti le fi han ọ ni wipe nigbati orun ba wọ nibi nigbana ni o di yiyọ ni iha ibomiran. Ọlọrun si niti aba ri oşu ni ki o gba Awẹ tabi Ileya gegebi ibere rẹ mofe fi kini kan ye ọ nipe Easter Monday kiniṣe ti iyen na ko je date kan, bi iti [Christmas] Kerestimasi nitori Easter yẹn lo fere jẹ ti Olọrun ninu odun Kiriyo nitori iyẹn ni nwon fi ṣeri ifeaumule ojo

Ikarun Olorun ko fi Esin rẹ si abe Ijoba tabi ikapa kan nipa bayi Esin Olorun [Islam] yato si Esin-kesin Esin alafia ni ti ko si pe tulasi Ijo ti Eko ba kirun Ibadan nilati ki be tabi Ilor'n nilati ki i be ayafi ti gbogbo wa gba be fi enikan se alase ofin esin lori wa bi [Khalifal] tabi bi Oba ilu tio ba ṣe pe labere ni ilu yoku wa.

Ekefa Moni ibere pupo lowo onibere yi lati bere [1] Mori ti awon onisọọ [Kiriyo] npe arawon ni oniṣbagbo ? Bibeli ni o pe nwon be ni tabi nrorikọ arawon ?



## Idahun Si Oro Lemomu Ajakuta

Olotu,

Jowo kunni a dun ti e ba le gba mi laye lati dahun si oro Lemomu Ajakuta pe Ki awa onigbagbo mase pe OLORUN METALOKAN MO!

Emi gbogbo pe oro Olorun ko ye Lemomu na ni, nitori enikeni ninu aiye gbo pe Jesu Kristi Omo Olorun ni I se ati re EMI MIMO ti o ran wa lehin Re si tun nse ise kanna. Nitorina ma toka lemomu na sinu Oro Olorun (Bibeli Mimo: JOHANU ori kewa ese ogbon (John 10:30) ati ori kedinlogun ese ekejilelogun (John 17:22; 16:7) Matthew 28:19; 3:16-17. Bakanna ni Johanu 16 7-13);

Nitorina nigbati Baba ran Omo Re wa si aiye o fi ohun gbogbo le Omo lowo. Nigbati Omo (eyiti ise Jesu) fe pada lo sodo Baba Re o fi ohun gbogbo le Emi Mimo lowo. Nitori idi eyi awon meta parapo nwon je okansoso nitori ise kanna ni won nse.

Olotu mo dupe aye ti e gba 'mi, Oko ota ko ni sa yin lese o. Oluwa yio tan imole Re si aiye olukulu wa amin.

## DOKITA AZIKIWE NILU AWKUSU



Aworan inu iwe wa yi niti "Dokita Azikiwe, en l'o so nilu Awkusu wipe asiko ave ti a fun Dokita Reform Committe ati awon omo lehin re lati ronupiwada ki nwon tumba ti pari ni ojo 14th osu July 1958

Bi nwon olote ona na ko ba tete ro kan se larin agfoni osu kan ti a fi si asun won yi, ki awon fi 'se atunse iwa won, so fi iya je won data-dare.


# DA EHIN-DIDUN RE DURO

nipa titete mojuto awon eree inu ati apo-ito re

LO

**DeWitt's**

**Kidney & Bladder Pills**

Ki o si bo lowo awon irora ti o nko e sinu arun

LAKUREGBE,
ARA-RIRO, EHIN-DIDUN
ati, Awon IYONU APO-ITO




**DeWitt's**

Kidney & Bladder Pills

L'arin wakati die ni wa a ti ri ayorisi ise re (ito' a mu awo miran wa)


## Isipaya Odun Ipeku 21st Ebibi (May)

Lati Owo
Gbadebo Dosumu

Eke pin, Eda pin, - Eke obinrin ku nile oko, lo ji ni'le Ale Oni omo biko'la ikola omo bi o gbeni ko gbeni A ki i- duro w oju oku li oja.

Ejigbomokun...———

Aisan:- Oniruru aisan yio yio wopo lodunni Etutu Etutu Etutu Etutu ni yio dinku die.

Aisoto:- Obirin Eke Eletan ati Alaisoto yio wopo l'odunni nitorina ki Enyin Okunrin o sora pupo lodunni lowo obinrin asiko

IBisi: Opolopo awon obinrin agan ati awon ti nwon wa ni Ebute "Ambe ni yio towo ala bosun lodunni.

Ere Oko yio po Fawon agbe lodunni sugbon ki a bebe ki opo ojo ma ba a je.

Aje: Ere mbe fawon onisowo sugbon ki won o yera fun jibiti on Fayawo.

Ijoba: Ki gbogbo awon Abogu - Basa o tera mo etutu ni i se ni orile ede yi ki Igbogua ti o ma si fun ijoba wa atipe ki awon ijoba wa o du lati fi otito se ipile ohunkohun ti awon yio ba dawole ki ijoba ma ba bo lati owo alase kan si owo enikeji fun aisotito. eyiyi nfe ebo gidigbi ebo inu kan ni ki aiye oru.

Otototo ororoto, ototo laje pa Ototo laje mumu ohun tori-tori ohun toretore lo f Oba Makin lodo Iranje ki o ba le fi ohun toritori ta wa lore. Da Orunmila o nlo gba aiye ti i se obiri Egberi Orunmila gba aiye tan Ifa nse e e e Ifa agba aiye lo egberi ko mo.

Aseyi-se-emi i. Ase.
Aboru Boye Bose


"The English Association of Accountants & Auditors. The English Association of Estate Agents & Valuers. The English Association of Secretaries. Founded 1941. Membership on Professional Experience, or Certificates with Reputable Schools, Colleges, Universities. 9, Charles St. Newport. Mon. Eng".

## E Gbadura Ki A Mase Ri Ajakale Arun

Lati Owo Iya Isaleko

Eyi ni iran ti Iya Isale Eko ri ti a si palase fun wipe ki o fururere kakiri agbaiye nitori ti awon ayanfe Olorun ti o mbe lori ile O ni ki a toro abo Olorun lori ara eni omo aya obi ebi ati ibatan eni ki Oba na mase je ki a ba won ku iku awoku Amin Iran na lo bayi:-

Loru ojo Monday 17th osu July 1958 mo ri ni iran oru wipe mo nfo ite ti omo yagbe si beni mo ri Daddy kan ti o te owo re mejeji bo apo sugbon awotele re je akisa. Eru re ba mi mo ngbon o ni ki nduro je ki mase beru beni mo si duro je

O so fun mi pe on fe ran mi si gbogbo aiye ati pe gbogbo oro ti o ba jade lenu on Olorun lo so o Ki nwi fun gbogbo enia pe ko si ife mo nile aiye iwa jamba ati ipania lo ku lati owo enikini si enikeji.

Bi o ti so bayi tan o gba ehin mi o si nlo. Mo bojuwo o, oun so pe lilo ti on nlo yi nilu Eko ni on lo titi on yio fi kari aiye O ni ki nwo oke bi mo ti woke mori awon irawo nlasla ati were ti awon mbe niri. Bi mo ti nwo o beni iran na lo loju mi

Nitorina e ronu piwada nitori ti ijoba Olorun ku si dede.

## Awon Olopa Fi Ideruba Fo Ilu Kan

KABBA Ogbeni Alege ti o nse okan ninu awon igbimo fun ilu Ode-ogbe lagbegbe ile Kabba so wipe, awon olopa fi ideruba le awon enia ti on nse oju fun ninu igbimo luko lori esin aj'omo-gbe tabi ako ji emo gbe.

Gegebi awon enia na ti beru olopa to awon enia bi egbeta-le legberun enia ti sa jade ti nwon si fi ilu sile, enikan ko si mo ibiti nwon kori si,

Agbo pe, ara awon enia yi ti awon olopa ti ko nigbekun, nwon nfi won se ise ipa bi elewon, nwon si nje won niya pelu.


## Igbadun wa ninu

## Oti Heineken's

Mu oti Heineken wo Oti
ti odara julo.
Kosi Oti miran ti odun
to o! Kosi oti miran ti
fun o ni idaraya! ranti: Oti
Heineken ni ale yio fun
o ni agbara ni owuro!




Agbara Pelu orun didun

# Oti Heineken

di Olokiki julo ninu gbogbo oti


## Koto Epo Ilu Bonny Ko Ni Epo Ninu.

BONNY Awon oyinbo elepo Moto ti a npe ni Shell-BP ti o nwa ile ibiti nwon yio gbe ri epo moto wa so wipe, koto epo ti nwon gbe nilu Bonny ko ni epo, lehin ti nwon ti gbe jin bi iwon ese metalegun lelogbafa nisale ile. Iye owo ti nwon na lori awon ohun elo ti nwon fi gbe koto na je Oke marunle-logota Poun.

Laipe ojo ibiti nwon tun nle dawo ni ibikan ti nwon npe ni Krakrama nilu Degema.

## Ijagbore Be Sile Nilu Kora

Edekoyede kan be sile nilu awon Kora eyiti o di ohun ti nwon ni lati yinbon pa oba won ti o je omo kekere, King Faisal, omo odun mejidilogun.

A gbo pe nigbati awon Tatanibulu gbo nipa oro yi o ba iwon ninu je ati pe awon omo ogun olote nworoyi to egbafa ti nwon taku ti awon Kora lehin.

Egberun marun ni awon Sailor ti Amerika ko lo lati gbeja awon kora.


## Kere o!

Ati ni orisirisi ogun German to sese de, fun onigbaru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.



No 73/S 2/Vol IX/697

## Ministry Of Home Affairs and Mid-West Affairs Information Division Western Region.

VACANCY FOR SENIOR INFORMATION OFFICER

Applications are invited from suitable candidates to fill one or more post of Senior Information Officer of the Information Division of Ministry of Home Affairs and Mid-West Affairs, Western Region Ibadan.

SALARY SCALE - C (E) 5, 6 pensionable and permanent. £1014 - 1140, £1188 - 1380.

For further particulars and method of application please see Western Region of Nigeria Gazette No 46 Vol 7 Notice No 645 of 10th July 1958.

CLOSING DATE: 31st July 1958


## Ile Ise Lentriki Gbarada...

EKO. Irohin kan wa ninu ose to koja wipe Ile Ise Onina-monamona (E.C.N.) ti bere si j'ere n'sisiyi, eyi je asiko ti a bere si se ise na ni ikawo arawa.

A gbo wipe ni asiko kan Ile ise na padanu bi oke medogbon poun, sugbon nisisiyi ti Ile ise na di tiwa loni ayipada nla l'o tide'be. Ere egberun marundinladorin poun ni Ile ise na je laarin odun 1957 si 1958.

Eyi fihan wipe ayipada nla de si Ile ise Lentiriki o si mu inu wa dun gidigidi gegebi Ile ise na ti nse eto fifi enia dudu si awon aye ti Oyinbo ti wa ri ti a fi le ri enia dudu marundilogota ti nwon ti gbe si ipo oga-agba ninu Ile ise na. Gbogbo oro nwonyi ni a gbo wipe Alhaji Ribadu ti ise Alabojuto ise ero so nibi apeje kan ti Ile ise Lentriki se ninu ile ijeun nla ti Ebute - Metta (Mainland Hotel)

Alaga Ile ise na Dokita Eni Njoku f'esi wipe l'ododo ni Ile ise na ti foju gba'lea pupo inu on si dun pe irani wo ijoba apapo mbe pelu awon ni gbogbo asiko na eyiti o je wipe Alhaji Ribadu ti ise Alabojuto ilu Eko ati ise Ero l'o mu iranlowo na ba won.

Ogbeni Jaja Wachuku ti o je okan ninu awon alakoso Ile ise ina lentiriki so wipe Ile ise na ti fu imi-'ka danu nisisiyi o si ti duro si oju ona ilosiwaju. Niti fifi enia dudu si aye ipo oga ako se eyi lati fi ma le awon oyinbo lo, sugbon ako ni gba awon alaninje laye awon si ise won ko moyan-lori.

## Adajo Da Iwadi Iku Omo Kan Duro

Otta. A gbo irohin wipe omode kekere kan ku sinu odo Ilogbo leti ilu Otta. Nigbati awon ri oku omo na gbe nwon gbe lo fun ayewo lati mo kini sababi ti o se iku pa omo na

Nigbati awon nfe se itose oro lo sibi iku ti o pa omo na Adajo so wipe sakala ni awon olopa kan fi enu kan oro na nigbati nwon gbe oro na de waju on.

Oruko omo ti o ku na nje Yekini Rufayi ti o ngbe abule Ilogbo.

(Koi ti pari)





## ORIKI BAMWO

Bamwo de, alajela omode agbomola bi orisa, akokoluko ogun ti nda'mo l'ekun igbona, atata ogun ti np'o tutu re warawara a je bi idan, a gba bi etu ibon. O s'abiku di ikugbagbe, o s'omo ti nbobin l'ore, Iko ri i sa, Iba ko l'ona tagiri, aiperi ri d'ekun iyonu Olugbala f'omo ti nyagbe orin o kapa inu wo, o lu jedi l'alapa, gbogbo abiyamo nyo sese, Ela ri i o roju, Orere ri i o na'gbe bo'ra, Eyi npa'iemo lodiieso, ore ikoko, kosemani awon abiyamo, eni araiye nlljedu ra. O de'lu Ibo, o doga, o de'le Hausa, o d'oba, gbogbo Onisegun 'o o pe ko legbe, gbogbo omode lo 'nfe e fun ilera.

*IGO KEKERE 2/6d IGO NLA 4s*
owo oko 1/6d fun Igo kan

THE EGBA TRADING ARADAN STORES

18, Denton Bridge, Street.
P. O. Box. 2 Ebute-Meta



## Freehold Houses For Sale

ITIRE ROAD ESTATE SURU-LERE

NEWLY BUILT DETACHED FREEHOLD HOUSES (THREE AND FOUR ROOMS)

**Prices From £1,320**

OVER HALF THIS ESTATE HAS NOW BEEN SOLD
INSPECT SHOW HOUSES AT RACE COURSE
REASONABLE MORTGAGE TERMS ARRANGED
FULL DETAILS FROM:-

**Lagos Executive Development Board**

(ESTATE DEPARTMENT)
RECLAMATION ROAD, LAGOS.
TELEPHONE: 20384


Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street P.O. Box 437 Lagos Phone 23??0